# IROHIN IMOLE

MOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No 1,573 TUESDAY NOVEMBER 30, 1965 (2D)

## Ojo Aawẹ Fẹ Da Edeaiyede Silẹ Larin Awon Musulumi

EKO:- Ninu irohin kan to de ile işẹ wa ni opin ọsẹ to kọja lọ yi ni Alhaji H. M Ọshinlokun ti işẹ Olori Ijọ Musulumi ti a npe ni "Tijaniyat Sect of Lagos" ti şe alaye ninu ọrọ rẹ pe awọn ko si ti ara mọ ikede kan to jade lati ẹnu Alhaji Makanju pe ọjọ kẹtalelogun oşu kejila ọdun yi ni nwọn yio kirun awẹ ti ọdun 1965 si ọdun 1966.

Alhaji Oshinlokun tun şe alaye ninu irohin rẹ pe gbogbo ọrọ ti nwọn sọ lori ikirun awẹ ni mọsalasi ijọ ti musulumi gbogbo gboo fun ilu Eko ni ọjọ kẹdọgbọn oşu yi ni o şe alaye pe ki işe otitọ ati pe awọn to şe ikede na ko tẹle eto ti awọn Musulumi lọna bi nwọn tişe gba şe eto ọjọ ti nwọn yio şe ikirun awe ati ọjọ ti nwọn yio gba awẹ.

Alhaji H. M. Oshinlokun tun şe alaye pe ki işe ọjọ ti o yẹ ki nwọn kirun ni nwọn şe ikede pe nwọn ni lati kirun awe ni ọjọ kẹtalelogun oşu kejila ọdun yi.

Oni ọrọ to jade nibi ipade eyiti awọn Imam, Alhaji, tabi awọn Olori Musulumi şe na ni ko tọna. O tun şe alaye pe ikede ti Alhaji Makanju şe pe awọn lodi si ikede na.

WO OJU EWE KẸFA

# AWỌN KAN YIN'BỌN PA ENIA MEJI NI IKẸNNẸ

IKẸNNẸ:- Gbogbo enia to wa ni ilu Ikẹnnẹ lo bẹrẹsi sa asala fun ẹmi nwọn ti ọlọmọ ngbe ọmọ pọn lori rogbodiyan kan to bẹ silẹ larin awọn ọmọ ẹgbẹ oselu meji eyiti awọn si yin ibon pa enia meji lẹsẹkẹsẹ ti nwọn tun dana sun ile olori ẹgbẹ Dẹmọ kan ni ilu na Alhaji Tijani Sofọla ti o tun jẹ Alaga Igbimọ Afunnishọ ti Ijọba ibilẹ ilu Ikẹnnẹ

Oniwe irohin wa ti iselẹ na şe oju rẹ fi ye wa ninu irohin rẹ pe iselẹ nla na şelẹ nigbati awọn janduku ọmọ ẹgbẹ oselu kan lọ kọlu ile Alhaji Tijani Sofola ti nwọn si lọ ja asia ẹgbẹ Dẹmọ ti o ta si oke ile re

Gẹgẹbi awọn enia na ti lọ fa asia na ja ni ẹnikan yin ibọn lati inu ile kan ti o wa nitosi ile Alhaji Tijani Şofọla eyiti o jẹ pe enia meji lo si ku lẹsẹkẹsẹ.

Irohin na tun fi ye wa pe awọn enia na tun dana sun ile marun ni ilu Ikẹnnẹ eyiti o jẹ wipe gbogbo ile na lo si jo raurau Awọn Ọlọpa si gbiyanju lati pa ina nla to şelẹ na şugbọn gbogbo ireti awọn Ọlọpa na si fọ lori apata lati le pa ina na.

Nigbati işẹlẹ na ti şẹle ni gbogbo awọn enia to wa sibi ayẹyẹ ọjọ ibi ti Oloye Iyaafin Awolọwọ ni ọjọ Aiku ti işe ọjọ kejinlọgbọn oşu yi ba bẹrẹsi ni sa asala fun ẹmi lori awọn ohunti o nşelẹ na.

Awọn ọlọpa ti gbe oku awọn enia meji na lọ si ile iwosan ti ilu Shagamu lati lo şe ayẹwo wọn ninu ile iwosan lakulaku.

Irohin tun fi ye wa pe awọn ọlọpa si ti pọ si gẹgẹbi nwọn ti wa tẹlẹ eyiti o jẹ wipe nwọn si ti bẹrẹ si ni yi ilu Ikẹnnẹ ka bayi lati ma wa awọn enia to jẹ wipe nwọn yio ran awọn ọlọpa na lọwọ lati mọ ẹniti o pa awọn enia meji na.

Oniwe irohin wa ni ilu Ikẹnnẹ tun fi ye wa pe gbogbo awọn obinrin ọlọja ti ilu Ikẹnnẹ ati agbegbe rẹ ni nwọn ti tun kọ ọja eyiti Ijọba ibilẹ ilu Ikẹnnẹ kọ silẹ ti awọn ọkọ awọn Obinrin ọlọja na ti lọ kọ ọja miran fun awọn iyawo wọn lati lọ ma na ọja nibẹ.

Irohin na tun fi ye wa pe gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ itesiwaju (UPGA) ti nwọn wa ni ilu na ni nwon fi işẹ wọn silẹ awọn agbe sile fi oko won sile ati awon osişẹ Ijọba ni ilu na ni nwon fi işẹ won si le lọ ko awon miran ni ọjọ ọjọ Bo ti işe ọjọ kedọgbọn oşu yi

Ni ọjọ aiku ti işe ọjọ kejidinlogbon oşu yi gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ itẹsiwaju U P G A ni ilu Ikẹnnẹ ati awọn agbegbe rẹ ati paapa julọ awọn to wa sibi ayeye ọjọ ibi ti iya afin Awolowo lo si pẹ sibi ayẹyẹ ti şişi ọja titun na ati pe orukọ ti awọn fun ọja titun na ni "Ararọmi"

Ninu ọrọ Agbọrọsọ fun awọn Obinrin ọlọja na fun oniwe irohin wa ni o ti şe alaye pe Ijọba ibilẹ ilu Ikẹnnẹ ti sọ oja ilu na di ti ẹgbẹ Dẹmọ N N D P ati pe ẹnikẹni ti ko ba ti jẹ ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ninu awọn ọlọja ni awọn Ijọba ibilẹ ilu Ikẹnnẹ fi iya njẹ won lati ọwọ awọn ọsişẹ Ijọba ibilẹ na

Ọkan ninu awọn ọga ni ile işẹ Ijọba ibilẹ ilu Ikẹnnẹ fun oniwe irohin wa ni o tişe alaye pe oja ti awon Obinrin ọlọja ilu na binu kọ silẹ yi yio ba nkan jẹ fun Ijọba ibilẹ na ati paapa julọ fun eto inawo ti Ijọba ibilẹ na

Oniwe irohin tun ran wa leti pe igbakeji ọga awọn ọlọpa ni ẹkun Ijẹbu Rẹmọ Ọgbẹni Thomas Oketunji ti pe ipade kan larin awọn Obinrin ọlọja ti ẹkun Ijẹbu Rẹmọ lati jiroro lori awọn ohunti o nşẹlẹ ni ẹkun Ijẹbu Rẹmọ şugbọn awọn Obinrin ọlọja na taku lati ba ọga agba awọn ọlọpa se ipade lati le jiroro lori ohun ti o nşẹlẹ ẹkun Ijẹbu Rẹmọ bayi

# DAWODU, O KU ORIRE

Lẹnu lọlọyi ni awọn enia ilu Eko nibo lati yan awọn Aşoju Ijọba titun miran sinu Ile Igbimọ Aşofin Ijọba Ibilẹ Eko; şugbọn ẹgbẹ Afẹnifẹre lo wọle ninu ibo na ti awọn di.

Enia mẹrindinlogoji lo wọle ninu awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ninu aye ijoko mẹjidinlogoji enia meje pere lo wọle ninu awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ.

Şugbọn nigbati awọn ọmọ Ile Igbimọ na şe ipade ninu ọsẹ ti o kọja lọ yi, awọn yan Ọgbẹni Dawodu ni Alaga Ile Igbimọ na dipo Alhaji Masha ẹniti o ti wa ni aye Alaga na tẹlẹ ri.

Oniwe irohin wa kan ran wa leti pe ni ojo Aiku ti işe ọjọ kejidinlogbon oşu yi ni Dawodu şe Aşiwaju fun awọn omo ile Igbimo Ijoba ibilẹ ilu Eko mẹjilelogoji eyiti işe ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alakuko lo si ilu Ikenne lati lo ba iyawo Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre iyaafin Awolowo şe ayẹyẹ ojo ibi re eyiti o fi ni di enu adota odun.

Awa Oniwe Irohin Imole ki Ọgbẹni Ganiyu Dawodu ku orire oko Ọba ko ni sa nyin lese o.



Aworan oke yi ni ti igbati Alhaji Masha nki Ọgbẹni Ganiyu Dawodu ku orire lẹhinti nwọn ti yan an ni Alaga titun.

# Iwe si Olotu Irohin Imolẹ

## Mo Ki Ẹgbẹ Afẹnifẹre

Dakuu Olotu gbajumọ iwe Irohin - Imọlẹ maṣe alai ko gba m ni aye rampẹ yi lati ki awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ilu Eko ku Orire fi abayori ibo eyiti ẹgbẹ na ko ni aye ijoko ti o pọju ti awọn ẹgbẹ yoku lọ.

Mo yọ fun wọn, mo yọ fun ara mi nipa iṣẹgun ẹgbẹ na nitori iṣẹgun yi ni o tun bọ fun ẹgbẹ Afẹnifẹre ni agbara ati ẹmi gigun ti o si jẹ ibanuje fun awọn ẹgbẹ Dẹmọ, o tun mu oju ti ẹlẹgan awọn abatẹnije.

Lakotan mo kan saara si gbogbọ awọn Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ilu Eko fun wahala ati iṣẹ ti nwọn ṣe ni asiko ibo Eko ni ti Ọlọrun si fi iṣẹ nwọn nyin wọn

Emi ni
AJẸGBORO — DAGBA
EKO

## ỌMỌ TITUN ALEJO AIYE

Ẹni ma bimọ ẹtọ ni koy ọ tun Ọlomọ ṣẹṣẹ ṣe mo ba Ọlọmọ yọ, Ọmọ titun lo ni ki gbogbo yin ngo si ki gbogbo yin l'ọkankan.

Ha! paripoto riboto mo gbọmọ jo mo ba Ọgbẹni Latifu Babalọla yọ nigbati mo gbọ pe Iyawo Rẹ Iyaafin Faliatu Arẹago bi ọmọ titun jojolo fun laipẹyi.

Gẹgẹbi erin ti mo kọkọ kọ si iwaju oke yi ni o mu inu mi dun pupọ nigbati irohin de si eti ngbọ mi pe Latifu Babalọla di baba Ikoko.

Adura si mi si Iya ati Babaọmọ na ni pe ki Oluwa o da ọmọ nv si ki o si fun awon obi omo na ni owo lati fi tọ omo na si ona rere Olorun yio si omo na ni olusire fun awon obi rẹ.

Ki nto p ri oro nimo be ogbe ni Latifu Babalola bab ikoko na pe ki o jowo ki o fi omo na fun mi fi ṣe aya nitori ojo ẹlẹje titu ni ẹmi omo Jalẹkun ẹ nwa, A o si ma won nipa rẹ.

Emi ni
ỌMỌ JALẸKUN Ẹ EKO

## Ẹ Ku Ọrire O!

Inu mi yio dun pupọ bi Olotu ba le gba mi ni aye kekere yi ninu iwe rẹ Oloyin mọmọ lati ki Councilor wa Alhaji O. J. Imoru ti WARD H1, ti a dibo fun wọle ninu ibo Ijọba Ibilẹ Ilu Eko.

Ẹ o ki Imoru pe o ku orire Oluwa yio ma ṣe amọna rẹ mo ba o yọ pupọ, ṣugbọn imọran si Alhaji Imoru ni pe ki o maṣe gbagbe awọn ileri to ṣe fun awa adibo ẹun yi papa lati ba awọn ọdọ ti ko riṣẹ ni Ward yi wa iṣẹ ki o si tun awọn adugbo Anikani tamọ ṣe.

Awa ara adugbo si tun nfẹ k nwọn ba wa tun awọn ile Abẹntẹ kọ ati ọja Ajelogo.

Imoru ao ma reti rẹ o, mo ki ọ pupo, o ku orire o.

Emi ni
L. A. Salami
EKO

## Balewa, Ẹ Rau Wa Lowo

Olotu inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye rampẹ ninu iwe oyin to kun fun ọgbọn ati oye lati kesi Alakoso apapọ Ijọba ilẹ Naijiria Alhaji Abubukar Tafa wa Balewa lati ṣe ohunti o tọ ti o si yẹ si Ipinlẹ Iwọ—Orun eyiti awọn enia Ipinle na si mọ pe eto ofin pajawiri lo tọ si Ipinlẹ na atipe ki nwọn si ko ibo ti awọn enia Ipinlẹ na di si Ile Igbimọ Asofin Ijọba Ipinle—Iwọ Orun ni ọsa to kọja ki awọn si ṣe eto idibo titun lehin ofin pajawiri



Alhaji ABUBAKAR

Eleyi jẹ ohunti o ma itoju ba orilẹ ede Naijiria lati ma gbo ohunti o nṣẹlẹ yi ati pe aiṣe otito awon enia Ilẹ wa nipa ona ti nwon gba ṣe eto Ibo na eyiti gbogbo wa mo pe ẹgbẹ UPGA lo bori Ibo na ti awon ẹgbe Ọlomo fi ona eru so pe awon lo bori ibo na.

Gbogbo enia lo han si lo ju pe ko si ẹniti o dibo fun ẹgbẹ Dẹmo lasiko ibo na la ko mo ona ti nwọn gba so pe awon lo bori ibo na e eyi yio fi dara bi Alhaji Balewa ba le lo ipo rẹ lere lati ṣe eto ofin pajawiri si Ipinlẹ na ki eto alafia a ifokanbalẹ le wa ni Ipinlẹ

Emi ni
R Olu Ọshinuga
Ibadan

# O Ti De Jaburata

Eyi ni lati kede fun awọnOnibara wa pe. Iwe Itumọ Ala. Iṣẹ Wiwo, ọjọ ibi Ọmode lati Oogun Ajẹbidan alapapo wa nilẹ fun tita nisisiyi, tete wa ra irẹ loni ki o to tan.

A si tun ṣẹṣẹ ṣe Iwe Itumo Ala miran ati iwe Joseph Alala

Irohin ko to afojuba 3/6d pere ni, ẹyọ kan, mejila tabi dosin rẹ jẹ 30/-

J. O. SHOYINKA
P. O. Box 159,
tabi 9, Iyala Street
Mushin.



Ọgbẹni J. O. Shoyinka

A si nfẹ awon ti yio ma ba wa ta awon iwe wa na

Tete wa si ọdọ Olotu
POPULAR PRINTING PRESS
9, Iyala Street, Mushin

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ATIOGO

NIPA **DYNAMIREN** TỌNIKI

ALE-BI-ALE Egbogi Tọniki amọnu tilun ti gbogbo ara ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akr agbara ati Ajẹbidan iṣẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.

Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣiṣe ti o ko le jẹun dara dara, tabi ki o male sun da da de ọkan lọsan tabi awọn ṣaa ara rẹ gbogbo ki ṣef un daradara ti Emi Breath inu ko ba kunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala sise tabi inu awọn ailera gbogbo nyia ti ọjọ ori (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun si aderi tabi jube lọ mọ daju pe DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara di tun patapata inu rẹ a jọlọ ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bi yabo dada Ara rẹ yio gbe kankan ni bakugba yio sao pẹlu igo aba durode o iyẹn dijb



Waterloo Medecine Store
8, Palm Church Street Lagos.
Phone 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

# ỌKUNRIN AGBẸ KAN W'ẸWỌN ỌDUN MARUN

IKẸJA:- Ni opin ọsẹ to kọja lọ yi ni Adajọ agba ile ejọ kẹkere ti Ikẹja paṣẹ pe ki ọkunrin ọdaran agbẹ kan Layọde Gesu yara lọ fi ẹwọn ọdun marun jura lori ẹsun ole jija eyiti awọn ọlọpa mu agbẹ na wa si ile ẹjọ fun,

Nigbati adajọ agba ile ẹjọ na ti se idajọ rẹ to ti bere lọwọ ọkunrin agbẹ na pe njẹ o jẹbi ẹsun na tabi ko jẹbi o si dia lohun pe on jẹ bi ẹsun na.

Ninu ọrọ ọlọpa to ba ọdaran na ṣẹjo ni o ti se alaye pe Layọde lọ fọ ile ọgbẹni Jimoh Ishola ati pe o si ti awọn ohun ini ọkunrin na pẹlu iwe ẹri ti ọkunrin na fi nwa mọto eyiti gbogbo iye owo ohun ti ọkunrin agbẹ na ji si jẹ pọn un mọkandinladorun ati şile mẹwa (£169 10/-)

Ọlọpa to ba ọdaran na şe ẹjọ tun se alaye pe ọdaran ọkunrin agbẹ tun lọ ji awọn golu eyiti awọn obin rin ma nfi si eti, ọrun eyiti gbogbo iye owo rẹ jẹ pọnun mejilelọgọfa ati şile mẹdogun (£122 15/-) ti iṣe ti Musiratu ti Mutiat ti nwọn jẹ iyawo Jimọh Isholа.

Ki adajọ ile ẹjọ na to şe idajọ ọkunrin agbẹ ni o bere lọwọ ọdaran na pe njẹ o ni ọro kankan lati sọ? ọdaran na si da adajọ na lohun pe on ko ni oro kankan lati sọ ni adajọ na ba şe idajọ rẹ gẹgẹbi a ti sọ si oke iwe yi.

Ninu ile ẹjọ kanna ni awọn ọdaran mẹta kan tun fi ara han niwaju ile ẹjọ na lori ẹsun pe awọn odaran na ji mọto ayọkẹlẹ kan gbe.

Awọn ọdaran mẹta na ni Rasiki Lawal, Sikiru Bello ati Ọladipọ Ọdukoya.

Ninu ọrọ Adajọ agba ile ẹjọ na ni o ti paşẹ fun Ọlọpa to mu wọn wa siwaju ile ẹjọ na pe ki o lọ ti won mọ itimọle titi ọjọ kẹtadinlogbọn oşu kini ọdun to mbọ eyiti o jẹ wipe awọn Ọlọpa yio tun şe iwadi ẹsun ole ti nwọn fi kan awọn ọdaran mẹta na.

Ninu ẹsun ti nwọn ka si awọn ọdaran na Ilrun ni Ọlọpa to ba wọn nşe ẹjọ ti şe alaye pe awọn ọdaran na lọ ji mọto ayọkẹlẹ kan eyiti nwọn npe ni Volkswagen ti iye owo rẹ si jẹ £750 nomba rẹ si jẹ LA 3457 ti işe ti ile işẹ United Trading Company.

Ninu awọn ohun ọşẹ ti Ọlọpa ka mo awọn enia na lọwọ ni ake, ada ati awọn irin ti awọn Ọlọşa fi nfọ ile.

Ọlọpa to ba awọn ọdaran na nşẹjọ ko jẹki ile ẹjọ na gba iduro awọn ọdaran Ọlọşa na. Ọlọpa to ba awọn ọlọşa na nşẹjọ Ọgbẹ ni Gaji tun şe alaye pe awọn ọdaran na yio di awọn Ọlọpa lori eto iwadi ti won nşe nipa oro na ati pe ki işe gbogbo awọn Ọlọşa na ni awon si ri mo bayi.


## APIAS RHUMATC & DRAGES

Jẹ ojulowo hanunhanun egbogi Jamani to lagbara gidi gidi fun iwosan LAKUREGBE" to mba enia ja

Orişirişi lakuregbe ni o wa lakuregbe Arungan ti o ma nsan enia ninu egungun ara lakuregbe ti o ma nwu enia ni ẹsẹ roboto ti o njẹki ẹsẹ wuwo lati ma rin Lakuregbe ti o ngbẹ orikerike danwo kori bi o ti rorun lati lo tabi ki o ma şe ayipada ẹsẹ, ara rita bi eyiti enia fi ata obẹ pa ibadi abi egogu ara wiwo, ako iba abi pipon tabi rirun.
Bi enia ko ba gbajumo lati toju rẹ lasiko o le so owo pa enia



WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palm Church Street Lagos
Phone.- 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)
LAGOS



# Kereo Kere o Akiyesi Pataki




Awa na le jẹri wipe Ojulowo hanuhanu Egbogi LEOPILLS awa na nlo ni Gold Coast (Ankara Ghana pẹlu meji rẹ ko si ninu gbogbo orisirisi Egbogi ti o wa ni Ilẹ Naijiria

A wa na njẹwọ ni Igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia tọmọde t'agba ni asiko yi ti nwọn fi şe ọrọ ati orin larin ara wọn nipa Egbogi Jamani olokiki yi ti nwọn npe ni LEOPILLS

Imọran awọn Dokita Oyinbo ti nwọn nşe iwadi Egbogi LEOPILLS, yi kan sọ wipe bi o ti lagbara to ati bo jẹ Ojulowo giriki ati atamatase fun "JẸDIJẸDI" bi o tiwu ki ọjo rẹ pẹ to tẹ na ni nwọn si tun fi ọwọ sọya tabi pe ileri fun gbogbo awọn ti amudi tabi iju, Igbẹ sise, aiko ri igbonsẹ deede, inurirun n'gbakugba ara wiwo, Ẹsan ẹhin didun sisan ati aiko riran kedere ko doro buruku lara, aisan Onigbameji ati orisirisi arun miran gbogqo pẹlu

"Wipe nwọn yio ri alafia ni kiakia ti nwọn ba nlo egbogi LEOPILLS nitoripe o tun ma tun ẹjẹ şe enia nipa sisọ di ọtun.

RANTI PE ALAFIA LOGUN ỌRỌ IJAFARA SI LEWU PẸLU.

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:— Igo nla si'e mẹfa abọ (6/-6 pere Igo kekere şile mẹta abo (3/6) pere. Ber Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi A nta ti e ba fẹ n Şọbu awọn:—

WATERLOO MEDICINE STORE
8, Palm Church Street Phone 22787
NIGERIAN MEDICINE STORES ALỌB
4, Tinubu Square Lagos
ATI NI ŞỌBU
IŞE OLODUMARE DISPENSARY OKE IBADAN
ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba


E Ma a Polowo Oja Yin Sinu Irohin Imọlẹ

